NYC Mayor's Office of Immigrant Affairs | Ọfisi Alága Ìlú ti Ọ̀rọ̀ Arìnrìn-àjò

# ÀWỌN OHUN ÀMÚLÒ FÚN ARÌNRÌN-ÀJÒ ÌLÚ NEW YORK

## KÒ NÍṢE IPÒ ÌWÉ ÌGBÉLÙÚ RẸ, ÌLÚ NEW YORK TI ṢETÁN LÁTI RÀN Ọ́ LỌ́WỌ́.

### Ìrànlọ́wọ́ Ọ̀rọ̀-òfin Arìnrìn-àjò

**Fún ìrànlọ́wọ́ ọ̀rọ̀-ofin arinrìn-àjò ọ̀fẹ́ tó sì ní ààbò pe 800-354-0365,** láti ọjọ́ Ajé sí ọjọ́ Ẹtì, Aago 9 Òwúrọ̀ sí 6 Ìrọ̀lẹ́.

### Káàdì Ìdánimọ̀ ti NYC

**Bèrè fún IDNYC,** káàdì ìdánimọ̀ ọ̀fẹ́ ti ìjọba-ìbílẹ̀ fún gbogbo olùgbé NYC láti ọdún 10 sóke. Sọdọ̀tun lórí ayélujára tàbí ṣètò ìpàdé láti forúkọsílẹ̀ **pe 311** tàbí ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/idnyc**

### Yàrá Ìkẹ́kọ̀ọ́ Èdè Gẹ̀ẹ́sì

Kọ́ **Èdè Gẹ̀ẹ́sì lọ́fẹ̀ẹ́** nígbàkugbà, níbikíbi. Ṣàbẹ̀wò sí **wespeaknyc.cityofnewyork.us** fún ọ̀pọ̀ alàyé.

### Ìtọ́jú ìlera

**Ìlera NYC + Àwọn Ilé-ìwòsàn (H+H)** H+H le pèsè ìtọ́jú pàjáwìrì, ìtọ́jú ìlera pàtó, àyẹ̀wò ara, abẹ́rẹ́ àjẹsára, àti síwájú síi. **Pe 718-387-6407 láti darí rẹ sí ibi tó súnmọ́ ọ.** Láti forúkọsílẹ̀ nínú àwọn ètò adójútòfò ìlera, èyí pẹ̀lú ètò **NYC Care** náà, pe **646-NYC-CARE (646-692-2273)** tàbí ṣàbẹ̀wò sí **nyccare.nyc**

### Ìlera Ọpọlọ

Fún àtìlẹ́yìn pẹ̀lú àṣírí àti ìsomọ́ ìlera ọpọlọ àti àwọn ohun àmúlò ìrànlọ́wọ́ ti ògùn olóró, **pe 888-692-9355 tàbí 988, tẹ ọ̀rọ̀ WELL sí 65173** tàbí ṣàbẹ̀wò sí **mentalhealthforall.nyc.gov**

### Pàjáwìrì

**Tó bá jẹ́ pàjáwìrì, pe 911.** Pàjáwìrì jẹ́ èyíkéyìí ìṣẹ̀lẹ̀ tó nílò ìrànlọ́wọ́ lójú-esẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ọlọ́pàá, ẹ̀ka iṣẹ́ panápaná, tàbí ọkọ̀ aláìsàn. **Nípasẹ̀ òfin, Ẹka iṣẹ́ Ọlọ́pàá Ìlú New York kò le bèrè ìwé ìgbélùú lọ́wọ́ rẹ ti ẹnití a ṣe ní jàmbá, ajẹ́rìí, tàbí àwọn míràn tó bèrè ìrànlọ́wọ́.**

### Ẹkọ́ Ìjọba

**Gbogbo ọmọdé ni NYC tó jẹ́ ọmọ ọdún 4-21 le lọ sí ilé-ìwé ìjọba.** Láti forúkọsílẹ̀, ṣàbẹ̀wò sí **schools.nyc.gov/fwc** tàbí **pe 311**

### Àwọn Ohun Àmúlò Ìlú àti Àlàyé Gbogbogbò

Ṣé o nílò láti ráyèsí àwọn ohun àmúlò ìlu tàbí o fẹ́ jábọ̀ ìṣòro kan? Pe **311** tàbí ṣàbẹ̀wò sí **portal.311.nyc.gov**

### Nọ́mbà Ìpè Ọ̀rọ̀ Arìnrìn-àjò ti NYC

Pe nọ́mbà ìpè wa ní **212-788-7654** láti ọjọ́ Ajé sí ọjọ́ Ẹtì, aago 9 Òwúrọ̀ sí 5 Ìrọ̀lẹ́, tàbí ímeèlì wa ní **askmoia@cityhall.nyc.gov**

Mayor's Office of Immigrant Affairs | Ọfisi Alága Ìlú ti Ọ̀rọ̀ Arìnrìn-àjò

# ÀWỌN OHUN ÀMÚLÒ FÚN ARÌNRÌN-ÀJÒ ÌLÚ NEW YORK

## KÒ NÍṢE IPÒ ÌWÉ ÌGBÉLÙÚ RẸ, O NÍ ÀWỌN ẸTỌ́.

### Yàgò fún Ṣíṣe Arúmọjẹ Ìwé-ìgbélùú

Tí o bá nílò ìmọ̀ràn òfin ti arìnrìn-àjò, lọ sí agbẹjọ́rò tí a fún láṣẹ nìkan tàbí aṣojú tí a fọwọ́sí. O le rí àkójọ àwọn olùpèsè tí a fún láṣẹ tí a sì dámọ̀ ní **nyc.gov/immigrants**

### Àwọn Ẹtọ́ sí Àfipámú Arìnrìn-àjò

NYC kìí ṣe àfipamú arìnrìn-àjò. Tí aṣojú ìjọba àpapọ̀ kan bá kàn sí wọ nípa àfipámú arìnrìn-ajò, o ní ẹ̀tọ́. Ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/knowyourrights** tàbí pe nọ́mbà ọ̀rọ̀-òfin arìnrìn-àjò wa lọ́fẹ̀ẹ́ ní **800-354-0365**.

### Àwọn Ẹtọ́ Òṣìṣẹ́

O ní ẹ̀tọ́ sí ìsinmi àkókò àìsàn tí a sanwó fún, owó ọ̀yà tó kéré jùlọ, ìsanwó fún àfikún àkókò àti síwájú síi lábẹ́ òfin Ìlú New York. Ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/workers** fún àwọn ohun àmúlo tàbí pe **212-436-0381**.

### Fi Ẹlẹ́yàmẹ̀ya Sùn

Ìdójútini àti ṣíṣe ẹlẹ́yàmẹ̀yà kò bá òfin mu lábẹ́ Òfin Ẹtọ́ Ọmọnìyàn ti NYC. Láti fi ìṣẹ̀lẹ̀ ẹlẹ́yàmẹ̀yà sùn, jọ̀wọ́ pe **212-416-0197**

### Ààbò Lọ́wọ́ Ìwà Ipá Abẹ́lé

NYC wà nílẹ̀ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ tí o bá ń dojú kọ ìwà ipá. O le ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/nychope** tàbí pe Nọ́mbà Ìwà Ipá Abẹ́lé ti NYC ní **800-621-HOPE**

### Àwọn Ẹtọ́ Ayálégbé

Ṣé o nílò ìrànlọ́wọ́ fún èyíkéyìí ìṣẹ̀lẹ̀ tó jọmọ́ lílé̩jáde tàbí onílé rẹ? Ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/tenantprotection** tàbí pe **311** kí o sì wípé **"tenant helpline" (nọ́mbà ìrànlọ́wọ́ ayálégbé)** fún ìrànlọ́wọ́ ọ̀rọ̀-òfin lọ́fẹ̀ẹ́.

### Ẹtọ́ sí Ibùgbé

O ní ẹ̀tọ́ láti bèrè ibùgbé tí o kò bá ní ilé lórí. Ráyèsí àwọn iṣẹ́ ibùgbé nípa ṣíṣe àbẹ̀wò sí ibi ìgbàwọle DHS tí a yàn. Kọ́ síi nípa pípe **311**.

### Ààbò Oníbàárà

Ṣé o ní ìbéèrè pẹ̀lú ìṣòwò bí? Gẹ́gẹ́ bí oníbàárà, o ní ẹ̀tọ́. Fi ẹjọ́ kan sùn nípa ṣíṣe àbẹ̀wò sí **nyc.gov/consumers** tàbí pe **311**